## Awọn ilana ti a le gba polongo eto idajọ laye ode oni

Ohunkohun ti i ba a ṣẹlẹ - iwa ipa sawọn obinrin, ṣiṣe awọn ọmọ lọna aitọ, iṣẹ, yiyanju rogbodiyan, ijangbara, ẹyamẹya, irinajo lati ilu kan siluu mi in, ẹtọ awọn oṣiṣẹ, ẹtọ awọn araalu, eto ilera, ọrọ ilẹ, ọrọ oju ọjọ - nipa awọn nnkan wọnyi, iwọnba igbesẹ la le gbe la i si eto ibarasọrọ tabi ipolongo to munadoko.

Gbogbo ọna la fi gbọdọ ṣe eto ti yoo mu agbelarugẹ ba igbe-aye, iyi, ati eto idajọ wa lọna igbalode, ki i ṣe eyi ti yoo mu abuku ba awọn nnkan wọnyi.

Awọn ilana ti yoo mu ki a le ba ara wa sọrọ lojukoju, lai pa ẹnikan lẹnu mọ, ka si jẹ ki ohun ti a n sọrọ nipa rẹ han si gbogbo eniyan, ki a jẹ ki wọn mọ aṣiri ohun gbogbo ti a n sọ, ki a jẹ ki wọn ni oye pataki ajọgbepọ wa, ati bi a ṣe le ba ara wa lo ni igbepọ alaafia.

Ninu itan eto to wa ninu ipolongo yii, awọn ilana yii lo le mu ki a ni awujọ ti yoo jẹ ki:

Ẹnikọọkan lẹtọ si ibaraẹnisọrọ, lati polongo, ati lati pin awọn imọ naa jakejado. Ṣugbọn awọn nnkan wọnyi nilo ohun eelo igbalode ti a le fi ṣe ipolongo naa, ati pe ki a lẹtọ lati sọ ohunkohun to ba wa lọkan wa tabi to ṣoju wa.

Ẹnikọọkan wa kopa ninu awujọ iroyin ati ibaraẹnisọrọ, paapaa fun awọn ẹgbẹ to ku diẹ kaato fun ati awọn ẹgbẹ ti ko lẹnu to lawujọ wa. Ọna ti a si le gba ṣe eyi ni pe ki gbogbo awọn tọrọ yii kan kopa ninu eto ipolongo yii lọna igbalode.

Ẹnikọọkan lanfaani si iroyin tabi ipolongo ti ko labula ti ko ṣegbe lẹyin ẹnikankan. Eyi nilo ka tẹle awọn agbekalẹ iṣẹ iroyin ati ipolongo, ka ṣe akọsilẹ ohun gbogbo, ka si ṣe atunṣe nibi taa ba ti kuna.

Ẹnikọọkan lẹtọ si iyi ati ọwọ. Eyi nilo ka ṣe akọsilẹ ohun gbogbo, ka jẹ ki ohun gbogbo han si gbangba fun awọn ti a n ba lo, lọna igbalode.

Ẹnikọọkan lẹtọ si aabo ati aṣiri iroyin wọn, paapaa ki wọn le pa awọn nnkan wọnyi rẹ nigba to ba wu wọn, niwọn bi ko ba ti tapa si ẹtọ ọminiyan tabi ti ko lodin sofin. Awọn nnkan wọnyi gbọdọ jẹ ohun ini ẹnikọọkan, ko si ni gbongbo ninu ofin to fun onitọhun lẹtọ ati ni nnkan aṣiri koun naa si ni aabo nipasẹ ẹtọ ọmọniyan.

Ẹnikọọkan lẹtọ si aṣa ati ede wọn. Eyi ni pe anfaani gbọdọ wa fẹnikẹẹkan lati ni aaye fun oniruuru ede ati aṣa, ati pe wọn gbọdọ lẹtọ ati le dari eto iroyin wọn lọna to wu wọn gege bi oni-nnkan.

Ẹnikọọkan lẹtọ ati sọrọ tabi ṣe iroyin lọna to rọ wọn lọrun ati nibamu pẹlu eto iroyin ti wọn mọ. Ọna ti a si le gba ṣe eyi ni ki a maa ṣe idanilẹkọọ loorekoore, ka si maa ba ara wa sọ asọyepọ loorekoore, ka maa gbọ ara wa ye, ka si maa ṣe aṣaro nipa ohun ti a jọ n jirooro le lori.

Ẹnikọọkan lanfaani si ohun to le mu ina wa fun irinṣẹ ti wọn maa lo fun ẹrọ igbalode wọn. Awọn ohun to le muna wa bii agbara oorun tabi ti atẹgun.

Ẹnikọọkan lẹtọ si awọn ohun eelo, irinṣẹ igbalode olowopọọku, tabi irinṣẹ ti ilu ti pese fun lilo awọn araalu sibi ti eto aabo to peye wa. Owo ti a le fi pese awọn nnkan wọnyi ṣe koko, bẹẹ lawọn to le tun wọn ṣe naa gbọdọ wa nitosi.

## About the language

Yorùbá is one of the principal languages of Nigeria and is spoken in some countries in the West African coast. An estimated 20 million people speak Yorùbá as their first language in southwestern Nigeria and more in the Republics of Benin and Togo.

## About the translator

Journalists for Christ International Outreach (JFC International) is a Christian media organisation devoted to spreading the gospel among journalists and other media professionals and using media skills to promote Christian activities in Nigeria.